# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. II. No. 78. SATURDAY, JAN. 5, 1924. FOURPENCE.



## DURO THOMAS.

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods.*

**"Specialities: Enamelware, Beer, Wine, Iron Bedsteads, Ruby Plates, Rubber Beads of all kinds, Clay and Briar Pipes, Champagne, Cement, Biscuits in cases, Gun Powder, Wire Nails Raugoon and original Ballam Rice, Accordeons, Piano, Padlocks, Beads, etc., etc., etc."**



**Circulation 1,000 Copies Weekly.**

EGBERUN IWE-IROHIN YI LA NTE LOSOSE.



## N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H. J. F. SICK ati AWON EGBE.

No. 7, Ita Ibode lailai, l'eti *Glover Memorial Hall*, (*Customs Street*,) EKO.





Awon Oyinbo Onisowo yi nranse MASINI-ARANSO ti a npe ni VESTA Nos. 1–4 t' olwo ati t' elese ni owo to roju, a le fi iye-owo won han enikeni to ba lo si Ile-owo yi.

Nwon mura tan lati se adehun pataki pelu enikeni to ba fe ranse Mejila tabi jube lo ninu MASINI na.

Awon Oyinbo yi nse orisirisi Ileke alarabara, nwon si nranse *Cement* ati panu kikole to nipon, ati eja abomafo ati orisirisi oja.

Ilekun Ile awon Oyinbo yi si nigbakugba ti enia ba fe lati lo ba won soro ASIRI nipa OWO. IROHIN KO TO AFOJUBA.

**J. C. VAUGHAN**

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun ẹkọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onişowo Irin Işẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ o.

**B. O. Joseph**

*Commission Agent.*

21 years experience in trade.

**Cotton.**
**Sundries.**
**Hardware.**
**Provisions.**

27, Koseh Street, Lagos.

Cable Address:—
"Steinafrik" HAMBURG.

**E. H. STEIN & Co.**

HAMBURG, Neurwall 16/18.
Hildebrandhaus.
*AFRICAN MERCHANTS.*

***ALL INDENTS EXECUTED.***
for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.**
*P. O. Box No. 505.*

Agent in Lagos:—

**Mr. Karimu Kotun**

Broad Street, & Portonovo Market Store.

ẸNIKEJI,

Aşọ Oke to yanju mbẹ lọdọ Iya Afin Saamọta Ikẹ Ọlọrun fun tita, ọpọku Ọyọku ni owo wọn, lọ bere ni 3 St. John Street, l'Eko, leti ile Johnson Agbẹjọro.

## ERO YA WA RA.

ADEBOYE ŞOLANKẸ Onişowo "Gbabiọgẹdẹ" ni Panu-kikọle ati kikan-ọkọ Işo lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun-ẹrọ, ati Ọşan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa l'okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Ile-ọja rẹ ni No. Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge St (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

OWO ỌJA RẸ FANIMỌRA.

Ẹ LỌ RA TIYIN NIBẸ.

*Editor & Proprietor:*—
ADEOYE DENIGA,
*Offices:* 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

**ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.**

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

—:o:—

ELEKO, Ẹ KU AṢEYẸ OJỌ.

A gbun si ni leti pe ni *Monday* (Atini) ọsẹ yi, Eleko ati awọn Ijoye rẹ Onifilafunfun diẹ lọ ṣe ẹyẹ didi'palẹ Iga titun ti awọn Ẹbi Oloye Onilẹgbalẹ npete lati kọ ni Isalẹ Eko; lati hle ni ọdun kẹta ti edekoyede ti wa nipasẹ ọrọ Eleko, eyiti o pa gbogbo ere bi Ẹyọ ati awọn ere wa miran l'oku, a tanma pe ọkinni ti Olowo yio kọkọ jade niyi, gẹgẹ bi Ipo rẹ bi Eleko.

A sọ fun ni pe ọgọrọ awọn Sanmari ilu lo pe'se nibi ẹyẹ na.

Nigbati a gbọ irufẹ ihin yi, a ṣe l'adura pe ki Baba A-yi-ni-pada-bi-iṣẹju, maṣai yi ọkan Gomina wa pada pãpã ninu ọdun titun yi, lati mu inu Eko yi dun si lẹkan si, nipa fifi ọwọ osi fa Eleko mọ'ra, ki o si dojuti awọn ọbaye-jẹ b'ọrun sejẹ.

ṢEUN, ẸNYIN ỌMỌ HALALI.

O jẹ ohun to dun mọ ni lọpọlọpọ lati gbọ pe awọn ọmọ Alufa Tijani Naibi ti ṣe baba wọn ni lilọ si Maṣalaṣi nla ni *Jimoh* lọsọsẹ lati ma lọ f. ara rẹ ṣe yẹyẹ ti o ni on nlọ kirun fun awọn kan; nigbati awa papa ri Alufa yi lẹnu ọsẹ kẹfa ọhun ti o nti ile bọ wa si Mọṣalaṣi nla yi ti o ntọwọ pẹlu awọn ọmọ-ẹhin rẹ ti nwọn si kọja lode Mọṣalaṣi na pãpã, kaka ki nwọn wọ inu rẹ lọ kirun, nṣe ni nwọn si wọ ile Alagba kan lagbegbe ibẹ, lọgan a ranti owe kan to sọ pe "Ki a ma ṣe gbe Sara kọja Mọṣalaṣi," anu si ṣe wa gidigidi, nitoripẹ mọ pe ṣiṣofo ni awọn ara wọnyi nfi koko ṣofo ni *Jimoh* ọsọsẹ ti nwọn ni nwọn nlọ ki lẹhin igbati awọn ilu ti yan Lemọmu Ligali rọ'po Lemọmu Braimah ologbe, ti Lemọmu na si ti bẹrẹ iṣẹ rẹ ninu Mọṣalaṣi na, nipa kikirun *Jimoh* fun awọn Janma lọsọsẹ.

A ṣọpẹ lọwọ awọn onilakaye ọmọ Naibi na ti nwọn kọ lati jẹ ki ẹnikẹni tun ma fi oye Elekuru gbọn-yẹyẹ lọ baba wọn.

A ni ireti pe awọn Apakeji Imale yi yio mọ riri "Ohun enia ti iṣe ohun Ọlọrun" ati pe nwọn yio si dẹkun ati ma jẹ ki awọn ọmọde ma ho le wọn lọsọsẹ *Jimoh* nigbati nwọn mọ dajudaju pe yio jẹ laifi fun nwọn lati wọ Mọṣalaṣi nla na lọ ki *Jimoh*, niwọn igbati awọn Janma ba ṣi wa nibẹ fun Isin Irun kiki.

A ti sọ titi o ti su ni pe ohun ti awọn Apakeji le ṣe lasiko yi ni pe ki nwọn lọ ṣe kokari ati ma ki *Jimoh* tiwọn ni Mọṣalaṣi miran fun sa kan na, titi yio fi rẹ ija; ọsa ki nja riri k'a wa riri.

IKORE TO GB'ỌWỌ.

Gba kan-nṣubu ni Isin Ikore ti a ṣe ni *Church Brotherhood* ni *Sunday* to kọja ninu Iwasu rẹ Pastor Iṣọla sọ nipa ti ere-ẹṣin ti awọn enia sa ni *Sunday* ọsẹ diẹ sẹhin, o sọ pe gẹgẹ bi *Sunday* ti jẹ ọjọ fãji tabi isinmi (kiṣe *Sabbath* ọjọ isinmi awọn *Jew*) ko si ẹṣẹ kankan ninu sisa ere ẹṣin na.

O sọ itan ṣoki nipa ohun ti o jẹ ki a mọ *Sunday* ni *Sunday* pe o jẹ ọjọ ti Ọba *Rome* kan ti a npe ni Constatine ni ki awọn Onigbagbọ igbani yi si ọjọ ti on Ọba na mbọ orun ti nwọn ba fẹ ki on lọwọ-lẹsẹ ninu Isin Kristi; eyi ṣẹlẹ ni ọdun 321 lẹhin ibi Kristi, ati pe lati igbana ni awọn onigbagbọ ti mọ ọjọ yi bi ọjọ isinmi tabi ọjọ fãji kuro ninu iṣẹ: ko si ẹnikan bi o ti wu ki o lagbara to

agbara rẹ ju ti Gidigidi lọ, ti ko le inmi ninu isẹ sise lẹkọkan; o si tun sọ ra ti ko wọ diẹ ti awọn *Church* miran i nipati tita ohun ikore wọn lowo-gere-nanyan ti ipa awọn ti nwọn ra miran ki tun ka mọ ti o si dibẹ di igbese si wọn lọrun; o sọ ti iwa itiju-pa-mi-ārẹ-epe ti awọn ọdọmọkọnrin miran ni nipa fifi ẹnu ya ẹran s'ọbẹ nipa bibu owo le ohun ikore ti wọn ki tto pemu rẹ ru mọ ni sisan; o si sọ pe Ikore ti *Brotherhood* yatọ si eyi nitori pupọ ninu ohun ti awọn enia mu wa kore ni a nfun awọn talaka ati awọn alaini. Ijinmi-ijinmi enia lo wa si Ikore yi l'ọkọnrin l'obinrin, ti aimọye wọn si duro gba ibukun; lai bu abusọ, gbogbo awọn to wa si Ikore na to ẹgbẹrun enia, b'olọ o ya mi ni awọn ọrẹ ati ojulumọ Ijọ yi fi ọna Ilupesi ṣe lọjọ na.

Ninu awọn to wa, a ṣakiyesi awọn ẹni wa wọnyi :—

Dr. O. Ṣapara I.S.O. Baba Ijọ na: awọn *Lawyer* Adedapọ Kayọde B.A. L.L.B., ati Olumuyiwa Jibowu B.A. (*Oxon*) L.L.B. Claudius Bowen ati ọrẹ rẹ kan, *Lawyer* H. W. Majarọ Williams, Ọgbẹni E. A. Akintan, *Editor "Eleti Ofe"* Ọgbẹni R. B. Reis, Olori awọn Ọlọpa-inu, *"Major"* Oke Adeṣigbin, Ọgbẹni Owo-iya Coker, Ọgbẹni Bagan Benjamin C.E. Ọgbẹni Bada, Ọgbẹni E. A. Marsh, Ọgbẹni Josiah Iroko ti Ebute Meta Iya Afin Mrs. Ayọ Peregrino, Iya Afin Mrs. Adel Williams Iya Afin Madam Cole, Iya Afin Mrs. Sweet Coker, Iya Afin Madam Maria Johnson Iya Afin Madam Sarah Adeṣigbin Iya Afin Mrs. Matilda Cole, Omidan Miss Sie Johnson ati ọgọrọ awọn ẹlomiran ti a ko mọ orukọ wọn tan.

Ẹ ku Ọba sin o, ẹnyin Ijọ *Brotherhood* aṣeyi ṣ'amọdun o.

## AJỌ IGBIMỌ AṢOFIN NKU FẸFẸ.

Gomina Agba Sir Hugh Clifford G.C. M.G. fi Apejọ keji ti Aṣofin Ilu *Nigeria* si ọjọ kọkanla oṣu to mbọ ni agogo mẹwa fi iṣẹju mẹdogun kọja larọ. Ilu, ẹ fi eyi sọkan o.

## IGBA MEJI, IGBA WIWUWO. IGBA BIBIMỌ ATI IGBA KIKU.

A jihin ni gbogbo *Church* Eko jake jado ni ale aisun ọdun titun yi pe gbogbo ọmọ ti a bi l'Eko ninu ọdun 1923 to kọja jẹ 2,900 ati gbogbo awọn ẹni to ku jẹ 2,110.

## ADENIJI APATA SIN-ABA. Ẹ KU'ṢẸ IFẸ.

Tayọtayọ ni a fi gba Iwe Ikajọ-oṣu ti ọdun yi ti Ọgbẹni wa R. Adeniji Martins ti 6 Ita Matiori (Oju erori) fi ṣọwọ si wa lọsẹ yi; Igbo-akan-mọ-pa ni Iwe Ika-ọjọ oṣu na, ile ti ko ba ti ni Iwe na ninu, ṣi wa ni ile yẹpẹrẹ.

## GBERE RẸ, ONIKANGA-AJIPON.

A gbọ pe ọrẹ wa Ọgbẹni Ben. O. Joseph ti Ita Akọsẹ, wà niti awọn Oyinbo Agbẹra (*Lagos Stores*) l'Ẹhingbẹti nisisinyi.

Ẹnyin Onibara rẹ, Ẹ lọ ri i nibẹ o!!!

## ILE LO LỌ KO ṢINA.

Mammy Susannah Jẹnkẹọ, Iya Ọgbẹni J. O. Beckley ti Olowogbowo (Ológbe) terigba'ṣọ ni *Thursday* ọsẹ yi ni'le rẹ, Ita Ọdunlami. Ọrun're o.

## AKIN ADEṢIGBIN, A-FINU-ṢENI-LORE.

Bẹ si ni a dupẹ lọwọ ọrẹ wa, Ọgbẹni Akin Adeṣigbin (*Tika Tore*) fun Iwe-ika-ọjọ oṣu ọdunni to fi bun wa lọsẹ to kọja; papin ni ẹwa Iwe na, ẹnikeji. Ọwọ a r'oke o!

## Ẹ KU EWU ỌDUN.

A ki gbogbo ẹnyin ara wa ni 'le, l' oko, l'ajo Ẹ ku ewu ọdun; ki ọdunni maṣai jẹ ọ̀dúndún fun gbogbo wa yika-yika.

## ONIBẸJU, A WA RI O!

Ọba Onibẹju de s' Eko ni oṣu tokọja fun ọrọ pataki kan lọdọ Balẹ Ilu Henry Carr, *I.S.O.*, o wọ s'ọdọ Aburo rẹ Ọgbẹni Abimbọla Ọjọmu ti Okepopo, o si pada lọ si ilu rẹ l' ọsẹ yi.

KITOYI?

A gbọ pe ni kutukutu hai ārọ ana awọn kan lọ tilẹkun Mọṣalaṣi *Jimoh* ni atipā ki awọn ti o nfẹ ki *Jimoh* nibẹ lọsan ọjọ na maṣe ri aye wọ'le. Eyi ki.

---

Agege,
29th November, 1923.

H. CARR ESQR, I.S.O., M.A., B.C.L.,
*Resident of the Colony,*
Lagos.

Sir,

We very much regret to observe the rather inconsiderable agitation that is being made by the Planters Union of Agege advocating the closing down of the Araromi Market and take this opportunity to respectfully submit this as a strong protest against the desire. The Araromi Market since it was started has at the suggestion of the Planters Union been changed to a day quite apart from the Agege Market day to avoid a clash and to afford the latter Market every scope for progress and if it has failed to achieve the expectations of its enthusiasts, the reason for the failure must be sought for elsewhere and the Araromi Market not blamed thereof.

2. We beg to state that the necessity for the Araromi Market is evinced by the fact that the district being an important centre of planting operations, much of the perishables must perish or deteriorate in quality and value and lose their refreshness and nourishing properties if kept to be disposed off only at the Agege Market. Hence the necessity for other intermediary markets such as the Araromi and Ayobo Markets for disposing of fruits and vegetables ripe and mature enough for disposal and consumption before the Agege Market day.

3. We would also state that we are quite prepared to still alter the day of holding the Araromi Market to any other day that the Government might consider advisable in order to afford every possible facility and avenue to the Agege Market. To close down the market however would entail much hardship and loss particularly to farmers or planters in the hinterland; farms who now find the Araromi and Ayobo Markets a great convenience. Besides it is respectfully submitted and will be readily conceded that these Market have acted even as feeders to the Agege Market in certain class of commodities which previously owing to the distance of the Agege Market were not being previously brought down.

It is hoped that this prayer will be favourably considered.

We have the honour to be,
Sir,
Your Obedient Servants.

For themselves and other residents at Araromi or Agege West.

---


## GOOD MARKET.

At H. Campos's Shops, 7, Campbell Street, 2, Faji Market, and 63, Ọdunlami Street, Lagos.

**NERVE TONIC.**

Moloke Mone A. & B. 6/- & 5/- a bottle.
Bula Matadi 7/- a bottle.

**WONDERFUL GONORRHOEA SPECIFIC WITH INSTANT RELIEF, WILL CURE THE MOST OBSTINATE CASES.**

Euregon Pillen Pills at 3/6d. a Packet.
Euregon Liquid 4/- a bottle.
Gramophone records 10 ins. & 12 ins. Best
Cigars superior quality. Provisions in endless variety.

CASH ONLY.


---

**CHANGE OF NAME.**

From and after the 1st January 1924, I, THEOPHILUS ABIMBOLA PHILLIPS, of 72, Okepopo Street, Lagos, and Railway Printing Office, Ebute Meta, desire to be known and addressed by my ancestral name

ABIMBOLA BANKEFA-OJOMU.

All documents letters, correspondence and agreement signed THEOPHILUS ABIMBOLA PHILLIPS by me prior to this date remain valid. Dated by me this 28th day of November, 1923.

T. A. PHILLIPS.

---

## Change of Address.

Mr. Karimu Kotun on behalf of his Firm begs to inform the Public that he is removing their Show-room from No. 20, Porto-Novo Market Street & Broad Street, Lagos, to No. 3, King Docemo Street, Lagos, (Babu Kaman Ala) with effect from the last day of January, 1924, and that all communications intended for him or his Firm from that date should be directed to the latter address.

# EKO AKETE.

EKO, SATURDAY, JANUARY 5, 1924.

## KABỌ, ỌDUN RERE, LA O MA WI TITI !!!

Lalai mọ ọmọ ti ọdun titun yi yio bi, ko yẹ ka fi ọkan ibanujẹ pade rẹ lọna, ki a ma bã fi awin ṣẹ ẹ lọwọ; pupọ ninu wa lo mọ pe bi inu ba ti ri l'oli nyan, nitorina a fẹ ki gbogbo enia sapa wọn nibikibi lati rẹrin musẹ si dide ọdun yi; ki nwọn si ti ipa bọ "ṣẹ" ero kero "lapa" ninu ọkan wọn.

A ti sọ asọye pupọ ninu Iwe-irohin yi nipasẹ ti ọdun *1923* ti a ṣẹṣẹ gbe oku rẹ sin ni lọlọyi, ko si tun yẹ loju wa lati ma tun so asọ idabọ nipa ti ọdun na mọ; "Oku t'oku k'a mi sun, awa ara wa l'a mi sun." Ọrọ awa-ra-wa l'oku ka mu sọ nisinsinyi, papa ninu ọdun 1924 yi. A o ha tun jẹ ki a fi Ọtẹ̀, Tẹmbẹlẹkun, Iwa "Eyi wẹ̀" ati aifẹni gbogbo ki ọdun yi kabọ bi? Kamari!

A o ha tun la oju wa silẹ ki tálubọ̀ kó wọ̃, nipa didiju si ohun ti yio ṣe ilu Eko wa yi ni rere bi, gẹgẹbi apakan wa ti ṣe l'eṣin nipa ọran a yan ni a ko yan ni lọ si Ajọ Igbimọ Aṣofin, ninu eyiti ẹlomiran mu ẹnikeji rẹ l'ọta apapa-ndodo titi di oni? Kamari!!

A o ha tun mã wà nipo ekute Ajẹ-ni-fẹ-ni, nipa didòṣìrì kά ọmọ alakeji wa, ẹniti a nfi ẹrin ati ọya-ya ki nigbakugba ti a ba ri i, ṣugbọn ti a nfi ẹnu yọ àlùbárikà lara rẹ̀ lọdọ ẹlomiran? Kamari!!!

Njẹ, o ku sọwọ olukuluku wa lati ṣakiyesi iwa ati ọrọ wa lọdunni, ki a si mã mọ̀ nigbagbogbo pe "A gbele mọ̀ kan ko si, awo lo wọ'nu awo," eyini ni pe iṣubu ati idide ẹnikẹni ko ṣẹhin ọmọ enia; ọkan ninu adura ti a ro pe o yẹ ni gbigba lemọlemọ l'ọdunni nipe ki a maṣe lọwọ si iṣubu ẹnikẹni, ki a si dù lati din iwa semi-nṣe ọ ku larin wa.

Adura keji ti o si yẹ ni gbigba ni pe ki Ọbangiji, Ọba Ogo, Eleti gbaroye, maṣai fi alafia Rẹ toju Imọran gbogbo lọ ji-nki olukuluku wa l'ọdunni tobẹ ti iku, papa iku obīnrin lẹhin ibimọ. tabi igbati o ba wa ni abara-meji, yio fi dinku; ti a o fi r'owo lo, ti òwò yio sin tun sọji, ti iṣẹ yio si ṣi silẹ lọpọlọpọ fun ẹ̀gbãgbèié alairikanṣekan ninu awọn arakọnrin wa to mbẹ ni lẹ yi ati ni ilu miran gbogbo.

Pẹlu gbolohun ọrọ meji, mẹta yi, ara, ẹ jẹ ka ko gbogbo aniyan wa le Oluwa lọwọ.

Nitotọ, a le ṣe ẹgbã aimọye ipinnu ṣugbọn a ti jẹ Awùsá kò tó ati mu'mi si, ati ṣe ipinnu, ko to a ti muṣẹ; melo-melo ni ipinnu ti awọn ẹlomiran ti sọ d'akisa kétè lẹhin igbati nwọn ti ba Olodumare ṣe tan.?

Nitorina ẹ jẹ ki a ma wa l'abo Ẹlẹda nigbagbogbo nitoripe:—

Nipa Igbẹkẹle Rẹ,<br>
Ki yio si nkan,<br>
Bi 1924 tilẹ ṣu dúdú bi ọ̀jọ̀,<br>
Ki yio si nkan,<br>
B'osi tun mọ'lẹ gãra bi Kristali,<br>
Ki yio si nkan!!!

---

## NOTICE.

### British Empire Exhibition (1924)

Owing to insufficient entries. prizes have only been awarded in one class, Native Cloth, out of the ten advertised for competition. The adjudication was kindly undertaken by Lady Clifford, C.B.E., and Lady Cameron who awarded the £3. 3. od Prize to Madam Ifabinu, Ado Ekiti. Special Prizes in this class have also been awarded to Madam Animotu, Ijebu Ode, £2. 2. od Madam Victoria Mobee, Lagos, £1. 1. od.

All other articles accepted for the Exhibition have been purchased at the price quoted by the maker.

---

## NOTICE.

### British Empire Exhibition (1924).

It is notified for general information that the Exhibition at Wembley Park will probably be opened on the 10th of April, 1924, though the official ceremony may not take place until 24th of April, 1924.

# LOOK OUT

**For the OPENING of**

# Lever Stores

## LIMITED,

## BROAD STREET, LAGOS.

A

## WONDERFUL ASSORTMENT OF GOODS

AND

## Nothing in the Store over 1s.

***"VARIETY AND VALUE."***

---

## ỌRẸ

Ẹ mura de ṣiṣi ṢABU TITUN ti awọn Oyinbo **LEVER,** Oniṣowo-Bombata, yio ṣi ni lọlọyi ni opopo nla ( *Broad Street,* Ile Bucknor.) Orişirişi Ọja ni mbẹ nibẹ ni ọpọku-ọyọku.

Kami-kami-kami ni gbogbo wọn njẹ, kosi-ohun-ta-fi nkan a, ẹnikeji.

## Ẹ WA WO.

## A-ŞE-JÛ BABA A-ŞE-TÉ.

[ *Lati ọwọ* ATARI AJANAKU. ]

Si Oni 'we-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ f' oji,

A nṣe, ile aiye li o ngbe, a ko si nṣe wa li ode aiye; ti a ba ṣe, kil' o ma dà, o wa ni idena orun, on li o da ifá fun Ṣõmọ ti o lọ gba Egun l' eti. Nigbati iwọ mọ, o ṣe ṣé e?

Odù-ifá yi li o yọ si iwe ti awọn Mammy o-niyẹri wa ko si Ijọba, ati esi ti nwọn ri gba. Ogún (20) obirin li o fi ọwọ si iwe na, ogún 'jọ oṣu December (20th) ni a si gbọ wipe nwon fi esi ranṣẹ si wọn; ogún enia kọ iwe, nwọn ri esi gba ni ogun 'jọ oṣu; ogun, ogun (Twenty, twenty) ṣà li o nṣe wọn si: nitorina, oro wọn ko le ṣe ki o ma gún, bi igbati nkan gúnwo.

Lẹhin ti Ijọba fi a-ṣi-sọ, a-sọ-dùn ati irọ ti o wa ninu iwe w n han won tan, o gba wọn ni imọran wipe, ohunkohun ti nwon ba ro wipe ko tẹ wọn l'ọrùn ni ilu, ki nwon fihan ẹnikan ninu awọn ti ilu yan si Igbimọ Aṣẹ 'lu. Ọrọ ti Ijọba fi pari esi na si Mrs. Ọbasa ni wipe :—

**"I am to suggest to you and the signatories to the Resolution that, if they desire their representations on any subject to be seriously considered by the Government, they should refrain from making dogmatic but wholly unfounded statements concerning matters of which they obviously have no knowledge. In conclusion, I am to say that the idea that all social and other improvements are only to be brought about by the active interference of the Government is not one which it is desirable to entertain or to encourage; and that self-help is a quality which might fittingly engage the attention of local philanthropists. So far as His Excellency is aware, nothing in the nature of attempts to render social service to their less fortunate and less instructed neighbours are commonly made in Lagos by the ladies for whom the signatories to the Resolution claim to speak."**

Itumọ eyi ni ṣoki ni wipe :—

*Bi awọn ti o kọ iwe si Ijọba ba fẹ ki a gba ọrọ wọn yẹwò ni ọjọ miran, ki nwọn ma ṣe sọ isọkusọ ati ọrọ ti oju wọn ko tó ṣinu rẹ mọ; ati ju bẹ lọ, awọn pāpā ni lati kọ bi a ti nran ara ẹni lọwọ, li aifi gbogbo nkan patapata silẹ fun Ijọba lati ṣe.*

Ire ati ilọsiwaju ilu ni lati jẹ iṣẹ olukuluku enia, t' ọkunrin, t' obirin, t' ọmọde, t' agba. Ajèjé ọwọ kan ko gbe ẹrù d' ori, ẹnikanṣoṣo ko si gbọdọ daba ati nikan gbe ẹrù ilu, ayaṣebi oluwa rẹ fẹ yọ ikẹ ọsan gangan. Bi ọkunrin ri ejò, ti obirin pa a, bi ejo ba ti ku, oran buṣe; ṣugbọn nigbati obirin ti ko le pa alangba, tabi eṣinṣin, tabi yanmuyanmu mu ẹyọ igbalẹ kanṣoṣo dani lati fi pa ejo, igi ko da bàun! Tabi tani ko mọ wipe paramọlẹ kọ ọrọ iwọsi?

Nitoto, aiye ti di aiye Oyinbo, ẹrú "nrọngadi" ọmọ Bẹni ni ilu Oyinbo papa, nibiti ọkunrin ngbọn jinni-jinni fun obirin, o ni ibiti agbara obirin mọ nigbati ọran ilu ba de 'lẹ. O si ni iye ọdun ti nwọn fi ṣe wahala ki nwon to ri aye diẹ kiun ti a fun wọn nisisiyi. Iya-ãfin, Mrs. Pankhurst ha le gbagbe nkan ti oju on ri, tabi o ha le ka iye igba ti on wọ Ẹwọn nitori ki obirin le li ẹnu diẹ ninu ọrọ ilu. Awon Mammy-oniyẹri wa ti o fi ara wọn jẹ oyè Iyalode-Eko, koi ti bẹrẹ si rá, ki nwọn to fẹ rin: nwon ko le joko, nwon nfẹ ṣe lákaláka: nwon ko mo ọna Ibadan, nwon fẹ gun Kẹtẹkẹtẹ de Ogbomọṣọ ni õjọ; nkan ti ọkọ ẹlomiran ninu wọn ṣe ti, ni aya wọn da 'wọle: ogo ni nwọn ri ko-ba-'kun-gbe èsi gba l'owọ Ijọba.

Gẹgẹ bi a ti sọ ninu Wosika wa ti íjelo, a ko ni ẹnikẹni si 'nu ninu awọn Mammy-oniyẹri wọnyi, a ko si ni ọta kanṣoṣo li arin wọn. Bi a ba si pode ẹnikẹni ninu wọn li ode nigbakigba, a o ṣí Akẹtẹ kí wọn bakanna, gẹgẹ bi àṣa Oyinbo ti o njẹ ki obirin ri ọkunrin fín.

Ni ilẹ tiwa, idọbalẹ ni ọmọde nki Baba, obirin ni lati ki ọkunrin ni ikunlẹ, ọkère si ni obirin ngbọ ohun orò. Ṣugbọn l'oni nkọ? Ọmọde a fi Sarotu (*Cigarette*) si ẹnu, yio si ti ọwọ mejeji bọ apo nigbati o ba nba ẹgbẹ Baba rẹ s'. ro, Ti Tommy si ri Louisa li ode, ti ko ṣí fila kí i, Louisa yio sọ fun ekeji rẹ wipe, aṣe bẹni Tommy gọ to, ti ko si li ẹkọ rara! o nki emi Louisa, ko ṣi fila. Ewo li o to ọrọ agọ ati aili ẹkọ ninu eyi? Ẹ ko wa ri bi ilaju tabi "Ṣi-fi-li-ṣá-ṣọ̀n" (*Civilization*) Oyinbo ti so Louisa ti a ba tà, ki a fi owó rẹ ra Atupa, di ẹni A-ji-tan-'na-wo li oru.

Oyinbo ko wa si ilẹ yi lati pa àṣa (*Native custom*) ilẹ wa run, ko wa si ilẹ yi lati pa orukọ wa rẹ, awa ni a nfi ọwọ ara wa ṣe ara wa. Ninu gbogbo iṣẹ ti o kun ilu, bi :—iṣẹ alagbafọ, iṣẹ aṣọ-riran, iṣẹ aṣọ-hihun, iṣẹ omọ-titọju, iṣẹ mọinmọin, abala ati nkan miran; iṣẹ Owo-ṣiṣe ni Muṣin, Oyigbo, Ikorodu ati ilu miran, ti obirin le ṣe, awon Mammy-oniyẹri ni ki Ijọba ba wọn wa iṣẹ—Emọ̀!

Ni ilu Oyinbo papa, ni ibiti Ijoba fun awọn obirin ni iṣẹ pẹ-pẹ-pẹ ṣe, ẹ ko mọ iye ọkunrin ti ko ri iṣẹ ṣe nibẹ—nwọn ju ãd jọ-ọkẹ (One and a half millions) enia lọ: ọgọrọ wọn li ebi si npa-ku li ojojumọ. Ki Ọlọrun maṣe jẹ ki a ri irufẹ inira bẹ ni ilẹ yi. Ju bẹ lọ, ilu Oyinbo ni a le ri obirin ti o ngbe Iyawo tan, ti ko si njẹ ki ọkọ sunmọ on, ti nwọn si nwipe awọn kò gbeyawo nitori ati bimọ, ilu Oyinbo ni a gbe nri obirin ti ko tilẹ jẹ gbeyawo rara, ka ma ṣẹṣẹ sọ ti ọmọ-bibi, eyiti o ba si jaja bi ọmọ kan tabi meji ninu wọn, o k'ogo ja. Ọmọ ni ayọ awa enia dudu, bi enia kọ pẹtẹsi mejila, ti Mọto (*Cars*) rẹ si pọ ju egbeje lọ, bi ko ba bi ọmọ—pabo ni!

Ka tilẹ wipe Ijọba gba ọjẹgẹ ati ma fi obirin sinu iṣẹ aranwe (*Book-binders*) gẹgẹ bi nwọn

wi, a o ma wo irufẹ obirin ti yio ṣe iṣẹ na ; yala bi adelebọ ni tabi wundia, bi aboyun ni tabi abiamọ tabi awọn to ti kan ti wọn s', oju kan. Ọpọlọpọ ọmọbirin kiriyo ni ko mọ atà lọ, ni ko mọ iyan gun, ni ko mọ ọbẹ se daradara, ni ko mọ ile tọju, ni ko tilẹ duro kọwe ni "Ṣukuru" daradara, sibẹsibẹ nwọn nfẹ ṣe iṣẹ akowe.

Nipa atunṣe ti awọn Mammy Oniyẹri ni ki Ijọba ṣe, awọn Mammy yi ha ti nsun ni lati ijọ-ujọ, tabi nwọn ṣẹṣẹ mọ ni pe irufẹ atunṣe bẹ yio dara fun ilu ?

Ọkọ meji tabi mẹta ninu wọn fẹ ki ilu yan nwọn si igbimọ Aṣelu ; *Legislative Council*. Nigbati ọjọ idibo pe, ifa wọn fọ 'bi. Ilu yan Lọya Shyngle, Moore ati Dokita Jones. Ko da ni loju bi inu awọn to bolẹ yi dun si awọn mẹta ti Ilu yan, lo u mi, o dabi ẹnipe awọn ti ẹran wọn bi obukọ yi lo ko si aya wọn labẹ lati ṣe iwe ti nwọn fi ranṣẹ si Ijọba : bi bẹko, ki lo ṣe nigbati nwọn ngbe iwekiwe a ya ojule awọn ogun obirin to fọwọ si i kiri, ti wọn ko ya ọdọ ẹnikẹni ninu awa awọn mẹta to pegede ; laika Erelu, laika olori ọba, aya onifila funfun ati awọn obirin ilu pataki miran ti a ti darukọ wọn ninu wosika ti a ṣe nijelo.

A ko fẹ ba ẹnikan wi pataki, ṣugbọn lakoko ti Dokita Ọbasa nduro lori agba ni Ilupesi, kiloṣe ti Iya afin aya rẹ ko ko ẹgbẹ rẹ jọ nigbana lati kọ iwe si Ijọba fun atunṣe nkan n'ilu, dipo eyiti o ṣẹṣẹ duro lẹhin oṣu kan ti Ilu yan enia tan ko to wa wipe on wa nibẹ? Enia pataki ni Mrs. Ọbasa jẹ ni ilu, nitorina lo se dun wa pupọ ati ri pe on fẹ gba ọna ẹburu wọ'le ninu ọrọ ilu. O ni lati juba gbogbo obinrin pataki Ilu, o si ni lati "foribalẹ" fun Ogbẹni Shyngle, Moore ati Jones to ba fẹ sọrọ ilu fun Ijọba, nigbana ni a le lamuso fun ohunkohun to ba wi. Ọlọrun ko f'orun kẹ Ogbẹni R. B. Blaize, ko si fi s' afẹtẹ rere.

Iwe irohin kan sọ fun wa pe, awọn Mammy to f'ọwọ siwe ti a nsọrọ rẹ yi mo iwe pupọ, ati pe awọn si ni ẹkọ to ye koro. Melo ninu wọn lo ka iwe irohin iṣẹ awọn obirin agbaiye to pejọ si ilu oyinbo (*London*) ni odun kẹdogbọn, 1899 ; iwe a npe ni "*Report of the International Congress Women*" ri Ẹni to ba ni ẹkọ daradara, yio mọ un to tọ lati ṣe, bi a ti ni lati ṣe e si, akoko ati ti o tọ si lati ṣe e.

P bẹ gbogbo ọkọnrin to ba ni aya, tabi iya tabi ọn, tabi aburo ninu awọn Mammy to kọ iwe i wọn fa nwọn l'eti, nitori apo ẹkun ki nse si ọmọ titun.

kita Savage ninu iwe irohin rẹ ti Satide ọsẹ ja wijọ pe ki Ijọba to f'esi ṣọwọ si awọn ny wa, gbogbo ilu ti fẹrẹ mọ iru esi ti Ijọba ṣowo, ati pe ọfọn ti a ko gbọdọ ṣ' oriṣa loju nibi iṣẹ ọba, pataki ni *Secretariat*. Bi o ba kita yi loju pe on ti mọ tẹlẹ nipa esi na ko darukọ akowe ọba tabi ẹnikẹni to sọ fun on, nigbana ni yio mọ nkan ti Ijapa npe ni oku ijọ mẹta, ab' oju rapata.

Lakotan, imọran ti a o fun awọn Mammy Oniyẹri wa ni pe ki gbogbo wọn lo parapọ lati wọ ẹgbẹ Tunluṣe ti a npe ni "*The Nigerian National Democratic Party*," bi nwọn ba si ka gbogbo enia to wa ninu ẹgbẹ yi si Aṣitani (*Cunning devils*) ki nwọn ma jafara lati lọ wọ ẹgbẹ *People's Union* ti awọn Malẹka (*Arch Angels*) nṣe ni Ilupesi, nigbana ohunkohun ti nwọn ba nṣe l'aiye, akala yio ma gbe orun mọ.

Emi ni ti nyin nitotọ,

ATARI AJANAKU.

---

**FRIENDS and COUNTRYMEN,**

**LET US SEIZE THE OPPORTUNITY OF THE DAY.**

Become a certified Medical Herbalist and learn how to alleviate human suffering by the skilful use of

***NON-POISONOUS HERBAL REMEDIES.***

The British College of Herbal Medicine of Bolton, England, prepares students to qualify as certified HERBALISTS by studying their Correspondence Course of Lessons.

For full particulars, apply to the Official Representative of the College :—

C. GLADSTONE-MACAULAY,
P.O. Box 384,
Lagos, Nigeria, W.A.

Remember that :—

*The more you know, the more you know how little you know*

---

FUN IRANLỌWỌ "EKO AKETE."

| | £. | s. | d. |
|---|---|---|---|
| Owo ti a ti ri gba ... ... | 8 | 16 | 6 |
| Ogbẹni N. A. S. ... ... | 0 | 10 | 0 |
| ,, Ben. O. Joseph ... ... | 0 | 10 | 0 |
| Ọlarẹwa-Ṣakin ... ... | 0 | 10 | 0 |
| ,, E. D. Adekunle ... ... | 0 | 4 | 0 |
| | £10 | 10 | 6 |

---

**WANTED**

**2 Lady News-paper Vendors.**

***With good Commission.***

**Apply to the EDITOR.**

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC. (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed. Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. (MORNING)

Masses Isin Arọ,

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S (Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENING. 5.45—6.30 p.m.

**ANGLICAN**

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | | Rev. J. M. Ologundudu |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Peter's (Alapako) | Rt. Rev. Bp. I. Oluwole |
| 6.30 p.m. | | (In charge) |
| 9 a.m. | Holy Trinity (Ebute-Ero) | Rev. S. J. Gansallo |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. David's (Jordan) | Rev. J. A. Leigh |
| 6.30 p.m. | | do. |

**WESLEYAN**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. A. N. Cole |
| 7 p.m. | do. | do. |
| 10.30 a.m. | Ereko | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 7 p.m. | do. | do. |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev. E. E. Williams |
| 7 p.m. | do. | do. |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | Rev. S. A. Pearce |
| 7 p.m. | do | do. |

**AFRICAN (COMMUNION)**

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | |
| 7 p.m. | do. | |
| 9 a.m. | Erelu | |
| 7 p.m. | do. | |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. E. A. Akiọla |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 6 a.m. | Zion | Rev. N. J. D. Shomuji |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Rev. I. O. Oyekunle |
| 4.30 p.m. | do. | do. |

**FIRST BAPTIST CHURCH**

10.30 a.m.
6.30 p.m.
9 a.m. Ararọmi (Baptist)
6 p.m.

**EBENEZER (BAPTIST)**

9 a.m.
6.30 p.m.

**BROTHERHOOD**

7.30 a.m. Ifupesi Resp'table Bro. Ariṇọla Ibara
7 p.m. Prof. Adeoye Deniga

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

**AHMADIA (ISLAM)**

6 a.m. Fajir Service I. A. Shitta
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajoṣe (Bamgboṣe Street.)

**COLONIAL CHURCH. (ODAN)**

8 a.m.—Holy Communion
6.45 p.m.—Evensong and Sermon; Rev. H. A. Lewis

**SALVATION ARMY.**

10 a.m. Lieut. Colonel George H. & Mrs. Souter
7 p.m. do.

**CHURCH OF GOD**

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m Open Air Service at Campbell Square, Edwin Mathew & Wm. C. T. Terrel

---


## IGBẸ L' OWO WÀ.

**LAGOS—EKURO.**

Bi awọn oyinbo ile-ọ̀wọ̀ wọnyi ti gba Ọja (*Produce*) l' ọsẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co.)
G. B. Ollivant,
Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores)
MacIver, African
Association, John Holt, Miller Bros.
Cooperative Wholesale Society Ltd.,
Jurgens Colonial Product.

£13—£15 fun *ton* kan.

EPO.

£24—£26 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a darukọ wọnyi gba *ton* k...

COCOA.

£14 10—£17 fun *ton* kan bakanna ...

KANO—COMPETITIVE PRICES.

Ground Nuts—£14—£15 per ...
Skins 1/9 per lb, Hides 5½d pe...

LAGOS STEVEDORING COMPANY.

ALL STEVEDORING WORK
undertaken at lowest possible prices anywhere in the Lagos area.

GOODS HANDLED CAREFULLY AND EXPEDITIOUSLY.

Estimates given for the handling of goods under any circumstances.

*PRICES ON APPLICATION.*
TO
**S. I. M. Johnson,**
9, Scale Square,
Phone 227 Lagos,
P.O. Box 498.

**Chairs! Chairs!! Chairs!!!**

For hire at Ilupesi Hall, Enu-owa, Lagos.

REDUCED PRICE, 1½D. PER CHAIR, PER DAY.

Apply to the MANAGER,
J. A. OSHODI,
26, OBUN-EKO STREET,
LAGOS.

**AGA, AGA, AGA.**

UN YIYA NI ILUPESI, ẸNU-ỌWA, LI EKO.
PỌKU NI A FI NYA NI NISISIYI,
(½D.) KOBỌ KAN PẸLU ABỌ.

Ọ si ọdọ ALABOJUTO,
Ọgbẹni J. A. OSHODI,
No. 26, ITA OBUN-EKO,
LI EKO.

**The Union Night School.**
FOUNDED JAN. 1923.

The School prepares candidates for Cambridge, Preceptors and Government Clerical Examinations and also teaches all Infant and Primary subjects, Yoruba inclusive.

The School opens on Mondays, Wednesdays, and Fridays in the Breadfruit School (Top floor)
For further particulars apply to

*THE SECRETARY,*
Union Night School,
P.O. Box 121,
Lagos.

ILE IWE ALẸ.

A da Ile-iwe alẹ silẹ fun gbogbo ọmọ Ile-iwe ati oṣiṣẹ pẹlupẹlu fun awọn ti o nfẹ lati ṣe idanwo fun iṣẹ Ọba ati *Cambridge*, a si nkọ iwe Yoruba nibẹ. A nṣe Ile-iwe yi ni ọjọ *Monday*, *Wednesday* ati *Friday* ni agogo meje abọ alẹ ni Ile-iwe *Breadfruit* (Loke.)

**GOOD BARGAIN**
IN
**Bunting Flags, Folding Chairs and Benches.**

CANNOT BE BEATEN.

Folding Chairs, Buntings Flags and Benches suitable for Picnics, Wedding Festivities, Entertainment, Social Gathering, etc., may be had on hire at the following very reasonable rates:—

FOLDING CHAIRS, 1½d. each per day.
FLAGS, etc., "Large" 6d. each, per day.
" " "Small" 3d. each, per day.

**Personal inspection invited. You are sure to be satisfied.**

Arrangements for delivery, etc., can also be made at very little extra cost.

Apply to:—SALAWU BANJOH.
*Manager,*
"Enia-Ṣoro" Cottage,
24, Porter Street, (Idunṣagbe,)
LAGOS.

# A. KESSLER,

7, Labinjo Lane. P.O. Box 459.

SAMPLE SHOW ROOM.

*Agent for* ARNOLD SCHLESINGER,

The German Trading House

Hamburg, Germany.

SAMPLES OF ALL GOODS FOR THE AFRICAN MARKET EXHIBITED.

The Mundlos Hand and Foot Sewing Machine.

as well as the Alder Foot Sewing Machines,

*Are always obtainable from stock or for order and are ornaments for every body's house.*

**FOR SALE**

The Typewriter "Perkeo" £9. 5. 0.

Cycles

Toys, that is what you want for Xmas.

24 hours Kitchen Clocks—a good clock for a good time.

Earthenware.

Descent Wristlet Watches, sh. 8/- and sh. 4/3 each.

Carpets to make your house comfortable.

Clay Pipes, Razors, Fez Caps, Hanging Lamps, etc.

As the fire wants the wood to burn, you want my Beer to quench your thirst, therefore buy the

LION BEER (Pilsener Light) 30/- per case.

TUCHER BEER do. 34/- per case.

And for happy hours take a case of my requisite CHAMPAGNE per case £3. 5. 0.

# JACOB AJAYI,

*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless variety at 50, Dosunmu Street, Lagos, at

***Prices to suit everybody.***

*Call now, fortune awaits you.*

## Aworan Alarabara.

A ni Aworan oniruru fun tita lati fi ṣe ile li ọṣọ. A ni ti titẹ oku Jesu, ti igbati a da a li ẹbi iku, ti Onjẹ-alẹ ikẹhin. A ni ti Adam ati Efa, ti iṣẹdalẹ aiye, ti Nebuchadenezar nigbati o wa ninu ọla rẹ, ati nigbati o di ẹranko; ti obirin ti o fi owo mu ejo, ati ti Ọba Tatambulu.

A ni ewe Taba fun kika ta, Ọṣẹ Olowo—agaga; Iyọ-iyọ mbẹ lọwọ wa fun tita bi wọbu, bi o ba fẹ ẹ ni *lọnu* a le ta a fun o. Iṣana Alapoti fun tita, ko si bi a ti nṣe wọn. Orisirisi oja lo wa lọwọ wa, iwọ ko le ba wa ṣowo ko ma jere tirẹ, nitori owo pọku ni a nta wọn. Owo ọja wa rọju rekọja ala. Bi o ba wa si ile-ọja wa "Ka mi, ka mi, ka mi" ni gbogbo wọn, bi o ba fẹ ja irọ wa, rin wa si ile ọja wa.

Iye owo wọn:—3d, 4d, 5d, 6d, fun ọkọkan; 2/6d, 3/-, 4/-, 5/6d fun mejila.

Ibikibi ti o ba ngbe ni *Nigeria* tabi ẹhin okun kọwe ṣowọ yala ni ede Gẹsi tabi ti Yoruba si:—

E. O. AMBE & BROS,
38, Moloney Bridge Street, Lagos,
(*Lẹgbẹ awọn Oniṣowo A. J. Tangalakis*),
Idumagbo, Eko.


## KNOW ALL MEN

That I, formerly known as

ISAAC AKINỌLA COLE

Builder & Contractor of No. 1, Market Street and 48, Breadfruit Street, Lagos Nigeria, desire to be known, called and addressed from the first day of January 1924 as

ISAAC AKINỌLA OGUNMỌDẸDẸ.

All Transaction, Documents, Papers etc., bearing the first name remain valid.

**Dated at Lagos this 24th day of December, 19**

I. A. COLE

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.